OWE
Oju ni a nmo aisi-epo, enu ni a nmo asiyo, obe ti ko ni eran idu-ro ni amo.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJO

Asoje
Igbala-ye, iye ko l'ayo-le.
B'ole lo-ni o le ro lola.

VOL. XIV No 810 LAGOS SATURDAY MARCH 10, — MARCH 16, 1962. KỌBỌ MEJI (2D)

# AWON OMO ILE IWE MEJO PADE AGBAKU IKU NILE IBO

ONITSHA—Awọn Omọde mejọ ti oruko wọn nje Godwin Okide, Peter Okide, Alphonous Okide, awọn ọmọ baba kanna paul Oziemena, Augustina Uwanwoke, Innocent Onyenweofo ati Anthony Onyenwofo awon ọmo baba kanna ni nwọn pade agbako iku gbigbona ninu ile iwe wọn ni Umuru Ideani l'ẹba Onitsha nibiti oluko wọn gbe ako wọn ni ẹkọ lọwọ ni aipe yi.

Onirohin wa sọ wipe bi oluko awọn ọmọde na ti ako wọn ni ẹkọ lọwọ ni owurọ ọjọ Iṣẹgun (Tuesday) ni ọkunrin kan pẹlu ada sare wọle ti o bẹrẹsi bẹ awọn ọmọ ile-ẹko na lori sile, ki oluko wọn to kigbe pe enia wipe ki nwọn gba on, ọkunrin apa,nia na ti be awọn mejọ lori ṣile, o si sa wọ inu igbo lọ.

Awon marun ni o je omo baba kanna ninu awon ti o ku na.

Awon Olopa si nse iwadi oro apa'nia na lowo.

LAGOS RACE CLUB

FEBRUARY MEETING 1962

NOTICE OF ADJUSTMENT OF RACING CALENDAR

Due to heavy rainfall, the Race Meeting fixed for Saturday, the 3rd day of March, 1962, was postponed until Saturday, the 10th day of March, 1962.

The Racing Calendar for the last three days of the meeting are therefore as follows :-

2nd day Racing - Saturday, 10/3/62
3rd day Racing - Saturday, 24/3/62
4th day Racing - Saturday, 31/3/62

I. A. S. Adewale,
CHAIRMAN
LAGOS RACE CLUB.

## Dandan ni Owo-ori, Tulasi Ni Aso Ibora.

EKO— Ninu ose ti o koja yi ni awon obinrin Eko yan enia mokandinlogbon lara awon Ẹgbe oloja ati onisowo wipe ki nwon lo fi oju kan Oloye Okotie-Eboh nipa oro awon obinrin ti nwon ni ki awon ma san owo-ori. Nigbati nwon de ibi iṣe Oloye Okotie-Eboh, Iyafin Young ni nwon fi ṣe asiwaju lati ba Oloye Minisita na soro.

Ninu oro Iyafin na, o ni ko ye awon idi re ti Ijoba fi so wipe ki awon obinrin wa san owo ori nitoripe opolopo awon ni ko si ise kan pataki ni ọwọ awon, nkan ko si lọ deedee fun ogunlogo awon ti o nta oja ninu awon ati pe opolopo awon ni o ni gbese l'orun.

Oloye Okotie-Eboh ni gbogbo alaye won ni on gbo ṣugbon on fe ki won mọ wipe gbogbo nkan mere-mere ti nwon nje anfani re larin ilu Eko loni owo ni awon Ijoba fi ṣe won, ati pe ko si Ijoba kan ti o le te owo bi o ba ti fe afi ki awon enia ilu l'okunrin l'obinrin perapo san owo ori won ki Ijoba le ri on bu na.

Oloye na si tun se alaye wipe awọn ti awọn fi si ibi ise owo-ori mo iru awon obinrin ti o nilati ma san owo ori yi. O ni ki ise awọn iya elepo pẹlu iya onlyọ, awọn ti owo ọja ere wọn ba ti le ni ọgọrun pọun ni nwọn yio ma san sile mewa.

Awọn ti nwọn ba si ri wipe nwọn ri to igba pọun tabi ju bẹ lọ a ma san pọun meta pere.

Dandan niti owo-ori o.!

NO. 34.

## Federation Of Nigeria
### THIRD DEVELOPMENT LOAN

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £7 million registered Stock in February/March, 1962. The Stocks to be issued will be:—

1. £2 million 5% Federation of Nigeria Third Development Stock 1966—to be repaid in full on 7th June, 1966.
2. £5 million 6% Federation of Nigeria Third Development Stock 1986—to be repaid in full on 7th June, 1986.

Both Stocks will be issued in multiples of £10 at par, and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the Central Bank during the period 26th February to 26th March 1962.

Prospectuses, which contain full information, and application forms may be obtained from banks or at the Central Bank on or after 26th February, 1962.

W. A. TIBBLES
General Manager

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
FEBRUARY, 1962.

## Adamodi Gomina De Kotu

KADUNA—Nitu Kotu ilu Kaduna ni nwon mu okunrin kan Audu Dan London ati awon enia meta wa siwaju Adajo fun esun wipe, o pe arare ni Gomina ipinle Ariwa, Oke-Oyr, ati awon enia meta yoku ni Ajele ati Igbakeji Ajele ati Akowe pataki fun won ni abule Makera nitosi Kaduna.

Audu Dan Londonu, eda ari yi tun so wipe Olotu Ijoba ipinle Ariwa, Olola Alhaji Sir, Ahmadu Bello ni o yan awon wa lati se iwadi lori ile ti nwon fi ntore ati ileti nwon ko laigbaseni abule na.

Dan Londonu ati awon enia meta na ni Ishaku Tudun Wada Audu Mainama ati Nababa Mainama ni nwon fi sun esun eniti o nfi enikeji elomiran pe arare lati se jamba jibiti.

Kotu paso wipe nwon ni ejo lati se o si fi gbegbo ejo na si ojo kejila osu March, 1962.

## Oro Riro Oloye Marun Loye

EKO— Oro ti a koko gbo nipa riro loye ti oba Adele fe ro awon Oloye marun loye ni ti Oloye Onilegbale, Salami Akinyele.

Ni owuro ojo Alaruba ose yi ni agogo mesan ni alagba Oloye na lo si odo akowe Alase ilu Eko fun wakati meta ni nwon fi soro po.

A gbo wipe Oloye Onilegbale so wipe oro ile meta kan ni o fa tababi aise derdere on ati oba Adele. Awon ile na wa ni 136 ati 138, Opopo Nnamdi Azikiwe l'Eko.

Awon ile na je ti Lisagba ti o je baba ti o bi Ologunkutere, Sokun ati Lanseran pelu Erelu Kutu ti o je iyawo re. Lanseran ku laifi omo sile, nipa be, o wa ku Ologunkutere ati Sokun lori ile na, a won ebi ile oye Sokun ti a npe ni Onilegbale wa bere ipin ti won ninu re.

O so pe on bere lowo Oba Adele ti o je ebi ti Ologunkutere ki o fun awon ni ipin ti won ninu owo ihaya ti awon ile na nmu wa. Eyi ni o bi oba Adele ninu ti o fi so wipe ki ama de Afin on mo.

(Wo yoku loju ewe kefa)

## O FI EHIN ENU GBE IRIN TO WUWO



DBENI Terry Downes ti anwo nitu aworan iy ni o ti gba oye "Abe'ese kun bi Ojo" ti o wa larin (Middle-weight Champion) ni o nse idanrawo nipa fifi ehin enu ro gbe irin ti o wuwo lati fun isan oruan re l'agbara sile de ojo ija oye re ti on pelu Pender ara ilu Amerika yio ja ni ojo kokanla osu July.

# Ejo [illegible]we Taba Igbo Ninu Kotu Ilu Eko

EKO - Ni ejo Monday to ti yi won nwen mu ejo ewe taba igbo ti nwen mba Onis wo eb'rin kan Agelina Ibiro ke Johns ni ro, wipe o fi ranse siiu Oyinbo ... daju ye riro ejo ra si ejo Karun osu March, 1962.

Y ye ejo na duro lo i aye ti Loya Ob'rrin Iyafin A. Acebiyi bere wipe, ... ko ni le maa ro ejo na lo ... meji ninu awon eleri ko wa.

Ad jo bere bi nkon ko baiti fun won ni iwe ipe ? ... s di h in pe nwon kot fun won, ati pe nitori cajo ... ki a gba odaran o ... naijeye lati ye ... nibi ajoga.

Ki Kotu to gba lati ye jo na ni obirrin na ti gb wipe on ko s irufe ... ti eja ti o wa ninu apoti ti nwon ti ri ewe taba Igbo ra ... tun Omiden Collier.

(Wo yoku loju ewe ...)

# E ma se fomi sofo




## E ki lo fun awon omo nyin ki won ma se fomi sere

E Ma Ka Iwe Irohin Eleti - Ofe Ti o kun Fun Irohin Aladun

# OLUGBIMO ASOFIN NINU IGBIMO ILU KENYA



Ogbeni Chana Singh ti o je omo egbe Kenya Freedom Party, ti o wole Igbimo Asofin fun Iha Gusu i'e Nairobi lati inu osu May odun 1962.

# OKU'JA WOLU

NIGBATI OJA KO BA TA, TI ENITI O RA OJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO SE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONISOWO LE SE TI OJA RE YIO FI MA TA BI ISU AKARA GBIGBONA.

## E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin Eleti - Ofe

# ELETI-OFE D'ARABA

# OKO OFURUFU ... GOMINA

AMERIKA.—Oko ofurufu kan ti o ko ero marun-le-ladorun ... ni a gbo wipe kete ti oko na si ni egbira ti o si ja lu'le sinu amajeje ira, idaji oko na yo si ode idaji wo inu omi, nwon ko lero wipe a le ri enia kan laaye ninu awon ero inu oko na.

Oko na nlo si Los Angeles lati ilu Amerika, nigbati o ja lule awon ti o ri oko na pelu eefin so wipe o ti njona ki o to de ile.

Eyiti o buruju ninu jamba oko ofurufu sele nile Amerika ninu osu December, 1960, nigbati oko ofurufu meji fori sanwon, ti enia merin-le-legbejo padanu emi won.

# Ejo Ewe Taba Igbo Ninu Kotu Ilu Eko

(O bere lati ju ewe keta)

Eleri kan, Ogbeni N. Nwuke ti o ndule de ega Bode obe, so wipe ise awon akowe Bode ri lati ye eru awon ero ti o nlo silu Oyinbo wo, gbegbo eyewo be ni lati je gedegbe.

Ogbeni C.H. Miller, Olori egbejoro Ijoba na Kotu wipe ejo yi i na Ijoba Apapo se lowo bi egba ponun.

Adajo fi ejo na si ojo karun osu March 1962.

# Gomina Titun Fun Ilu Gibraltar



Oga'gun agba, Sir, Dudley Ward, Oloye nla G.C.B,
K.B. E, ati D.S.O., ti o ti nse wolewode fun Alaiye-
luwa Oba Obinrin Elizabeth ni nwon yan ni Gomina
ati Alase Pataki fun ilu Gibaltar dipo Oga'gun
Sir, Charles Keightley, eniti asiko ati fise sile re yio
to ninu osu June, yio bere ise re ni arin odun yi.

A bi Oga'gun Sir. Dudley Ward ninu odun 1905,
o sii lo eko iwe nilwe giga ti Wimborne ati Sandhurst.

# ALASE OHUN OGBIN-OKO NILU TANGANGIKA



Ogbeni Derek Bryceson, ti o ti je Alasa Ilera ti tse ninu Ijoba ni o padu di Alase ohun ogbin-oko ninu Ijoba Tanganyika, ichin ti Olori ijoba na fise sile ichin osu meji ti nwon gba Ominira ilu na.

Ogbeni Bryceson je omo Gesi ti o ti di ara ilu Tanganyika, Ogbeni Nsilo Swai ti o ti je Alase oro ni o gba ipo re.

# OBA ADELE KOLE RO MI LOYE BENI OLOYE OLOROGUN WI

EKO—Oloye Tijani Babalola, Olorogun ilu Eko eni kerin ninu awon Oloye marun ti Oba Adele so wipe on fe ro l'oye ni igbo wipe o fi owo so siya wire Oba na ko to eniti o le gba fila lori on rara.

Oloye Olorogun so oro yi nigbati o lo fi oju kan Alase ilu Eko lose ti o koja, Oloye nawipe on ko ni ija kan ti pelu Oba Adele ti o fi de ibi wipe o fe gba fila lori eni.

Oloye Olorogun yi ni on yio se atako Oba Adele de ibi ti ko ni le bu ete lu ofin ibile ati-eyi joye a nroniloye ni ilu Eko mo.

Eni odun mejidinladorin ni Oloye yi, o si di odun k rinla gbako ti o ti gun ori oye.

Ju gbogbo re lo awon Egbe omo Ibile Eko pelu awon asiwaju esin Imale ati Onigbagbo ni nwon ni awon yio pari ija awon Oloye nwonyi pelu Oba Adele mba ise won lo ni aiduro.

## E wo Awamoto Oniwa-kuwa




Ko bikita fun ofin oju opopo-ona, ti o fi lo kolu moto miran ti o tun lo kolu eniti o nfi ese rin.
ENYIN AWAMOTO, E SORA.

## Ijoba Fe Ti Ile Ise Alapako Ni Ijora

EKO - Laipe yi ni awon alase ijoba ile Nigeria se ikede wipe awon fe lati ti ile ise alapako ni Ijora Ijoba (Saw Mill) ti ijoba da sile lati iwo bi odun mejilelogoji to lo ni niter po ile ise na ko fa owo wole fun awon mo ati pe opolopo iru ise ti o njade nibe ni awon osise miran nta nse, eyi ti o si mu oku a ba r.

(Wo yoku loju ewe kefa)

## ODARAN KAN GUN ADAJO L'OBE NITORI OWO-ORI

IJEBU-ODE- Laipe yi ni Kotu adajo Ibile Ijebu-Ode ni okunrin agbe odaran kan ti oruko re nje Olaitan Odunsi, ... ogoji odun ti a nu ejo re wa si kotu wipe lati bi odun marun s hin ni o ti ... fun owo-ori sisan, fa obe yo ... t o s fi gun okan ninu awon adajo ti o so wipe ki o san ... ati ... owo-ori ateh nwa tiko ti san ati ... o fi p ... tan-ran tabi ki o lo ... awon ... kan pelu ise ajekara.

Bi awon ... da ejo na tan ti awon adajo na ni ki awon ko si iyewu ... d ran na ba f'ole yo ti o si fi gun okan ninu awon adajo na, o ... ejo ti awon da on ko te on lorun rara. ... awon olopa si ti te, nwon ni awon yio b se ejo wipe o fe pania.

## Ejo Ewe Taba Igbo Tilu Oyinbo

EKO - Ki adajo Kotu Eko to fi idajo si ojo kokanle-logbon Osu March yi, ni Loya obinrin Iyafin Adebiyi ti o wa fun odaran obinrin Onisowo, Angelina Ibijoke Johnson fi siwaju adajo wipe, apoti ti nwon so pe ewe taba Igbo wa ninu re na, ki ise nkan ti owo miran ko le to Iehinti awon gbe fun Omidan Kehinde Collins ti o je okan ninu awon oleri Ijoba.

(Wo yoku loju ewe kefa)

## OWE YORUBA

**Agba kosi ilu baje, bale ile ku ile dahoro.**

**Enia ko dabi Allah Oluwa ni pe ko yeni. Makan-makan ni oye nkan enia.**

# NIGERIAN PORTS AUTHORITY

## INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of the undermentioned scrap materials now lying on the Authority's premises:-

| Lot No. | Description | |
|---|---|---|
| 1. | 3 Coles Crane Nos. 1, 3 and 4)<br>1 Ransome Rapier Crane No. 2) | ) as one lot |
| 2. | 1 Mirg Crane K. 5000D | |
| 3 | 23 Lead Acid and Alkaline Batteries ex Craft | |
| 4. | 15 Easy Chairs<br>9 Writing tables<br>4 Mirrors on Stands<br>3 Bed Frames<br>2 Pairs Bed Ends<br>1 Chest Drawers | ) as one lot |
| 5. | 22 Refrigerators Electric<br>10 Cookers<br>7 Water Heaters<br>8 Ceiling Fans | ) as one lot |
| 6 | 4 Typewriters Nos. 6A59064x6E05781x)<br>21400x481317) | )as one lot |
| 7 | 1 Lighter No. L.50 | |
| 8 | 1 Lighter No. L.54 | |
| 9 | 144 No. 44 Gallon Drums<br>101 Carbide Tins<br>40 No. 2 Gallon Paint Tins<br>383 No. 5 Gallon Paint and Nail Drums<br>78 No. 10 Gallon Grease and Snowcem Drums<br>718 No. 4 Gallon Kerosene Tins | ) as one lot |
| 10. | Quantity of Steel ex Lightbuoys etc. | |

2. The above items may be inspected on application to the following Officers of the Authority between the hours of 8 a.m. - 12 noon and 2 p.m. - 4 p.m. not later than Thursday, 15th March, 1962.

Lots Nos. 1 - 6 Senior Stores Officer, Apapa Quays
Lots Nos 7-8 Dockyard Manager, Apapa Dockyard
Lot Nos. 9 - 10 Senior Stores Officer, Apapa Dockyard

3. A Copy of the Tender Form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, on payment of £20 to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays. The completed Tender Form should thereafter be returned to the Secretary to the Authority in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL - TENDER FOR SCRAP MATERIALS" so as to reach him not later than 4 p. m. on Friday, 23rd March, 1962.

4. The successful tenderer will be required to pay for, cut (where necessary), and remove the scrap materials at his own expense within 7 days of the acceptance of his offer. The deposit of £20 will not be refunded in any event to any tenderer, who upon being advised of the acceptance of his tender, fails to pay for, and remove the materials as stipulated.

5. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority

N. P. A. Notice No. 697.
2nd March, 1962.

# ORO RIRO OLOYE MARUN LOYE

(O bere loju ewe keji)

Awon alagba meji ninu ẹliu ile oye Onilẹgbale ni o ba Oloye lọ si Ile ise Alase ilu Eko, awọn Ogbẹni Mustafa Onilẹgbale ati Rabiu Onilẹgbale wọn je ki nwọn ba Oloye wọ iyara ti nwọn ti sọrọ.

Oloye Onilẹgbale yi ni o de fila oye ni 19th osu February, ọdun 1943. A gbọ wipe on ni igbakeji ọba.

Nis'siyi o di Oloye meta ti o ti lọ si Ile Alase ilu Eko ti nwọn lo sọ ti wọn. Awọn ni omoba Aminu Muse Kosoko, Oloye Asajon, Oloye D.A Ogunlana, Obanikoro ati Oloye Salami Ak'nyele Onilẹgbale.

Awọn Oloye meji ti o wa ku lati lọ sọ ti wọn ni Oloye Tijani Babalola Olorogun, yio lo loni Satide ati Oloye Lam'di Yesufu Kalefo Keji, Olumeghon ti yio lo ni ọjọ Alaruba, ọjọ keje osu March, 1952.

# IJOBA FE TI ILE ISE ALAPAKO NI IJORA

(O bere loju ewe karun)

Logan ti awon osisọ ile isẹ alapatako yi ti gbo ifilo yi ni nwon ti fi ake kori, ti nwon si nlọ ibosi gbẹ ẹ wipe, nibo ni ijoba yio fi ti awon si? "Ona ofu, ona orun, iyawo ati awon omo wa nke, a ko ni bọ won ni"? Nwon tese bo sokoto, awon ati awon alabakedun won," nwon si gbe asia kotewa-lorun, nwon dori ile Ọlola Tafawa Balawa, Oloru Ijoba Nijiria wipe ki o ba awon gbe oro na yewo.

Ọlola Tafawa Balewa na yoju si won o si ba won kedun pupo o ni ijoba fi dwon s'okan sugbon nitoto ni ijoba npadanu pupo lori ile ise alapatako na, ijoba si ti se ipinnu lati ti i.

# EJO EWE TABA IGBO NINU KOTU ILU EKO

(O bere loju ewe karun)

Iyafin Adeleyi dur lori wipe ẹsun ti awon fi Angelina ṣun na ko suna mu ofin Anunimuye, gqolokun ,ohun ti a mu jade nilẹ Nigeria" o ni om dan Collids komu gba ona tara jade nitoripe o ti mo wipe ewe taba Igbo ni on nnu ios ilu Oyinbo, ni ko joki o le mu gba ona tara ti awọn

awon osisẹ Bode yio fi yewo.

O so wipe ki Kota fun Angelina ni asfani iyemeji nitoripe awon eleri alatako ko ba arawon dogba."

(Iyoku di ọsẹ to mbọ)

Printed & Published By The Union & Publishing Company 28, Kosoko Street P. O. Box 467 Phone No 23370